ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LEJO . . .

VOL. XIV N0 845 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 17—NOVEMBER 23 1962 KỌBỌ MEJI (2D

Pagidari !

# Awon Alapata Yo Oloye Yekinni Ojikutu Lolori : Nwon Ni Ko Ko Iwe Egbe Wa

EKO—Ọrọ bẹhin yọ, awọn alapata ẹran ti o wa ni Eko, ni Ebute-Metta, Sabo ati Apapa mọ Agege fi aake kọri wipe awọn kọ Oloye Abudu Yẹkinni Ojikutu ni baba ẹgbẹ awọn ati pe awọn si fẹ ki o ko gbogbo ẹru iwe awọn pẹlu nkan miran ti o jẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ti o wa lọwọ rẹ wa fun baba-ẹgbẹ tuntun ti awọn ṣẹṣẹ yan, Ọgbẹni Lawani Madojutọla.

Onirohin "Ele-Ofẹ" ti o lọ si ibi ipade gbogbo gboo ti awọn ẹgbẹ alapata na ṣe, ni ọrọ ti nwọn sọ nibi ipade na kiṣe yẹyẹ rara ; nwọn ni suru, lobi, o si tun lakọ, nwọn ni awọn ti ri i pe Oloye Yẹkinni tiṣe igba tirẹ ṣugbọn ẹniti awọn ri wipe o le sin awọn de ibiti ẹru ko ni ba awọn ni baba-ẹgbẹ tuntun ti awọn ṣẹṣẹ yan yi.

Ọkan ninu awọn ogunna gbongbo ti o wa nibi ipade na sọ fun mi wipe awọn ti fi ẹda iwe pe awọn kọ Oloye Yẹkinni Ojikutu ni baba-ẹgbẹ, awọn ranṣẹ si Minisita Alamojuto ọrọ ilu Eko, Akọwe Minisifa ilu Eko Dokita Onimọtoto ilu Eko, Minisita alamojuto eto irohin ati gbogbo awọn Kansilọ tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ yan si ile igbimọ Minisifa (Lagos Town Council) ati Olori awọn akọwe Wolewole.

Awọn bi Alhaji Kelani ti Ebutẹ-Mẹtta, Baba Olo ti Mushin ati Shomolu, Alhaji Tijani Ọladọtun (akọwe) ati Lasisi Arẹmu pẹlu awọn miran fọwọ si iwe na.

LAGOS RACE CLUB

Second Day

NIGERIAN TRADE FAIR RACE MEETING.

T O D A Y

First Race at 3 p. m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10. 0d; 2nd £1. 10/– and 3rd 10/–.

Come One Come All

Hon. Secretary
Lagos Race Club.

Sangba Fo !

## Dokita Maja Kekere Tu Asiri Awon Olote O Ni Awolowo Ran On Ni Nkan Ija Ogun

Eko — Ṣangba fọ ni owurọ ijarun tiṣe ọjo Iṣẹgun nigbati awọn Ọlọpa bẹrẹsi ro ẹjọ ọtẹ-gbigbona ti nwọn mba Oloye Ọbafemi Awolọwọ, Olori awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) pẹlu awọn enia merindinlọgbọn miran ti nwọn mu pẹlu rẹ, ni Kotu-ganran ni iwaju Adajọ-agba, Ọgbẹni Geoge S. Ṣowẹmimọ.

Ki nwọn to bẹrẹ lati ma ro ẹjọ na, Ọgbẹni B.A Adedipẹ tiṣe agbẹjọro Ijọba sọ fun adajọ wipe awọn ko ba awọn meji, awọn Dokita Ọladipọ Maja ati Ọgbẹni Richard Babaiọla tiṣe igbakeji akọwe ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) ṣe ẹjọ mọ, awọn si fẹ pe awọn mejeji ni ẹlẹri Ijọba ninu ẹjọ ọtẹ na.

Gbara ti awọn Ọlọpa ti tu Dokita Maja silẹ kuro ninu apoti awọn arufin ni nwọn ti ni ki o bọsi inu apoti ẹlẹri lati ro tẹnu rẹ. O ni on mọ Oloye Awolọwọ bi ẹniti o mọ owo. On niran ọjọ kan ti on lọ sọdọ rẹ lati lọ ṣe alaye fun un nipa ọrọ on ti ẹnikan sọ fun un ni aidara.

( Wo yoku loju ewe kejọ )

# Awolowo Ni Ghana

(O bere loju ewe kinni

Ni ibiti awon gba nfi oro je omitoro oro pelu Awolowo, Maja ni nigbati Awolowo toka si bi nkan ti nlo si segesege si ni Nigeria, on ni a mu de odo Asoju Ijoba ile Ghana ti o wa nihin yi boya o le ri iranlowo kan se fun un. On si le be. Nigbati Awolowo pelu Asoju Ijoba Ghana pade awon ni o pe ki Awolowo alara paa ya lo si ilu Ghana lati lo fi oju kan Dokita Nkrumah Ti se Alakoso Ijoba Ghana.

Saju eyi, Maja ni nigbati Awolowo foju kan Asoju Ijoba ile Ghana ti o wa nihin yi, oro ti o jemo atubotan ilu enia dudu (Afrika) jake-jado ni awon so - ero awon si ba ra won mu lori oro ti to si ni Afirika na.



The quest to extend the grass-growing season through winter is explained to Mr. Bisade Onayinka, from Ososa, Western Nigeria, during a recent visit to the Royal Dairy Show at Olympia, London.

Mr. Onayinka, who is a government agricultural officer, is now in England on a three-year course at the Grassland Research Institude at Hurley.

He is looking at the pictures and diagrams of grassland in Morocco and Portugal. Below them are samples of grass from these contries which have been cultivated in England for research. Explaining the exhibit to him is Mr H. W. Rogers, of the Plant Breeding Institute, Cambridge. The exhibit shows that even with the use of fertilisers and special grass varieties, there is still a long gap between autumn and spring in the grass-growing season.



OLOYE AWOLOWO

Lehin eyi Awolowo te oko leti o lo si ilu Aganyin lati lo ri Alakoso Ijoba Ghana Dokita Nkrumah O ni on ri Awolowo lehinti on ati Nkurumah se ileri wipe on a ran awon omo egbe Afenifere lowo nitoripe oro ti nwon npe nipa atubotan ilu enia dudu bi a ri i won mu

## Egbe Osise

Maja ni awolowo ni on (Maja) ni lati ran awon lowo ki awon mo iru iranlowo ti awon egbe CPP egbe Ijoba ilu Aganyin na a se fun awon. O ni nigbati on de ibiti nwon gbe nko awon odomode ti nwon pinnu pe awon yio fi han on, o ni oko ti won egbe osise ti mbo ti adie ati malu pelu ibi nwon tun nfun wa ra ni nwon fi han on wipe ibe ni awon yio ti ko awon omo ti egbe Afenifere (AG) ba mu wa nitoripe orisirisi igbesiaiye ni awon nko awon omo won nibe.

Maja ni lehin eyi on tun lo si ilu Aganyin lati lo ri Nkrumah sugbon on ko rii nitoripe o ti lo si ilu awon Rosia (Russia). O ni nigbana ni nwon so fun on wipe ibiti awon fe ma ko awon odomode na ko ti pari. O ni bi nwon ko awon omo Nigeria lo sibe lehinna on ko le so rara.

## Kise Te Je

Eleri yi ni lehinti nwon de mo'le ni o tun ranse si on wipe ki on, ki on lo si Ghana lati ba on ra nkan ija-ogun nitoripe oro yi ti kuro ni yeye googbo Yoruba ni o bawi, o ni ti o ba je wipe Dokita Azikiwe tabi Okpara ni nwon hu iru iwa bayi si, nkan a kan ni, isele ase ni Nigeria. O ni Awolowo ran si Ogbeni S. G. Ikoku pelu owo ti o ni ki Onabanjo ko fun on ki on le fun Ogbeni Ikoku na. O ni on ko owo na fu Ikoku sugbon o ni ojo kan ologun ti on ra kun inu moto, oko eja ti on fe lo ko ni le ko on, ni on ba pada wa sile.

## Ojo Agan

O ni nigbati on pada de ti on ko le ko awon eru na wa si Nigeria, awon wa tun oro na ro wipe ti o ba se tieu ti nwon fi nfo okuta ni awon le ri ra jaburata ni Kudri (Quarry) ni Abeokuta. Maja ni awon un okunrin kan lowo ni Abeokuta fun ota ifokuta na.

Maja ni ero ti awon se fun ojo ti awon ko ba pe ni ojo Agan ni September 22 ti o koja ni pe awon yio fi agbara gba Ijoba Apapose lowo Alakoso Ijoba Alhaji Tafawa Balewa ni oru ojo na, awon yio mu Alhaji Ribadu pelu agbara ati Oga awon Olopa, Oga awon Soja, awon yio si yi ile Gomina-agba ka ati ile gbogbo ile ibise Ijoba. Sugbon Awolowo ni awon ko gbodo ta eje enikan sile rara ti awon ban se eyi. O ni ti awon ba ti se eyi tan, Awolowo yio lo soro sinu Redio ni Ikoyi pe on ti di Alamojuto Ijoba Apapose

Nwon ti suu ojo ejo na firo si ojo Ojobo (Alamis ojo mefa loni.

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (10)

## (Lati Owo Omo Abati)

Ninu itan mi ni ọsẹ ti o kọja mo sọfunn ẹnyin ọkawe mi wipe awọn ọmọ Ẹgba ni awọn ti o mọ ẹto orin kikọ ṣe ninu awọ ọmọ wọn. Awọn ọmọ Ẹgba ni o kọ laju si a nlọ si ilu Oyinbo lati lọ korin sinu awo gbohun-gbohun ti nwọn npe ni gramophone record ti o di yẹyẹ ni Nigeria ni ode ti isisiyi.

Ologbe alufa J. J. Ransome-Kuti je ẹniti o fẹran orin pupọ, o si ṣe arofọ orin Yoruba pupọ nigba aiye rẹ. Bẹna si ni ọmọ rẹ "Dawodu" Ologbe alufa I. O. Ransome-Kuti tiṣe Oluko ilewe giga ni Igbein ni Abẹokuta nigba aiye rẹ. Orin meji ni Pa Kuti fun awa Ẹgba gẹgẹbi orin ibilẹ (national anthem) ni iwọn ọdun mejilelogoji sẹhin. Ọkan ninu meji na ni mo tẹ jade fun nyin ninu iwe itan mi ni ọsẹ ti o kọja, ikeji ni eyi :

(1) Kabiyesi Ọba Alake,
Ademọla Keji,
Ọmẹ Erin Jogunọla,
Ọmọ Ọtẹnkan,
Kabiyesi ! Kabiyesi !!

(2) Awa ewe Abẹokuta,
A yin 'Luwa logo,
Fun anu ati ore rẹ si Ọba
Ademọla,
A si nkọrin ogo,
Ogo ! Ogo !!

(3) Fi ẹbun ati ore Ọfẹ Rẹ,
Tẹ Ọba wa lọrun,
Ki ade ko pẹ lori rẹ,
Ki bata pẹ lẹsẹ,
Ki a si mọ kọrin,
Kabiyesi.

Eyi ni ikeji orin ti Ẹni-owọ Ologbe Alufa J.J. Ransome-Kuti kọ a a ọmọ Ẹgba ti a nlọ si ile-iwe nigbati nwọn gbe ade fun Ọba wa Alaiyeluwa Ademọla Keji ni 27th September 1920-ọdun mejilelogoji nisisiyi. Nigbana awọn ọlọpa onifere ilu Ẹgba ko ṣe fi ara we rara. Ati ọmọ ilewe pẹlu awọn akọrin Ọlọpa yi ti nwọn npe orukọ wọn ni E. N. A. Police Band ni nwọn jọ kọ ni orin yi pọ.

ORIN KUTI

Orin yi duro fun gbogbo awa ọmọ Ẹgba bi orin God Save the King ti duro fun awọn Gẹsi ti nwọn ba nyẹ Ọba wọn si nibikibi. Gbogbo awọn ọmọ Ẹgba igba ọjọ na lọhun ni nwọn mọ awọn ohun ti nwọn kọ wa lati fi kọ awọn orin ibilẹ Ẹgba mejeji na.

Alo ohun ti a njo yi fun iwọn ọdun mẹrindinlogun gbako ki "Dawodu" Ologbo Alufa I. O. Ransome-Kuti to de ti o si fun awọn ọmọ ile-iwe ilu Ẹgba ni orin ati ohun tire ni iwọn ọdun mejidinlogbọn sẹhin.

Ologbe Alufa I. O. Ransome-Kuti jẹ ọmọ bibi inu Alufa J. J. Ransome-Kuti, alufa Ijọ Ṣọsi C.M.S. ni Akẹ l'Abẹkuta. Ọpọlọpọ ọdun ni Alufa Kuti fi ṣe iṣẹ tiṣẹ-agba ni ile iwe giga ti npe ni Ijẹbu-Ode Grammar School ni Ijẹbu-Ode. Ọpọlọpọ awọn ọmọ Ijẹbu ti o di enia pataki pataki ni aiye oni ni Alufa Kuti kọ ni iwe.

O pada si ilu Abẹokuta ni iwọn ọgbọn ọdun si igba ti a wa yi. ọdun keji lẹhin na o wa ko orin kan (gẹgẹbi ologbe baba rẹ) fun gbogbo awọn ọmọ ile-iwe ilu Ẹgba ti nwọn ni lati ma a kọ fun ẹyẹ Ọba Alake nibikibi ti awọn ọmọ ile iwe na ba mba ṣe ẹyẹ. Eleyi ni ọrọ orin ti "Dawodu" na:

(1) Kabiyesi Ọba Alake
Ademọla Keji,
Ọmọ Erinjogunọla,
Ọmọ Otẹnkan,
Kabiyesi Ọba wa ,Kabiyesi (2ce)

(2) K'Ọlorun Ẹgba ko tọju-yin.
Nitori itobi Rẹ,
Kọjọ nyin dọjọ alẹ,
K'aya ile balẹ,
Kabiyesi Ọba wa, Kabiyesi (2ce)

IJAIYE

Boya ni a le ri ninu awọn adajọ, lọya, dọkita awọn oselu pẹlu awọn enia pataki lọkunrin ati lobinrin ti nwọn kọ ẹkọ iwe ni ilu Abẹokuta ni iwọn ọgbọn ọdun sẹhin ti nwọn yio wipe awọn ko mọ ohun ohun orin yi. "Dawodu" ọrun re !

Gẹgẹbi mo ti sọ ninu itan mi ni ọsẹ ti o kọja wipe orin "ADEMỌLA JỌBA ILU TORO NINI" ni orin pataki ti awọn Ẹgba kọ lojọ ti nwọn ngbe ade fun Alaiyeluwa Ọba wa na ; awọn ỌMỌ IJAIYE ni o kọ orin na.

Ko si ẹniti o le wipe bawo ni ti awọn ara adugbo ti a npe ni Agọ-Ijaiye ni Abẹokuta ti ri ni Afin Alake, nitoripe Ologbe PẸLU Onilu ni agbole Adan ni Ijaiye ni Onilu Ọba Gbadebọ nigba aiye rẹ, on na ni o si lu ilu gangan lojọ ti Ọba ngbade. Aburo rẹ, Akanni, ni onilu Ọba Ọshinlẹ Karunwi ti awọn Ẹgba pa ni Ọba ni 1918 ninu Ogun Adubi. Ilu ati orin mbẹ lọwọ awọn ọmọ Ijaiye.

(Koi ti Pari)

"Iyeru Omo Olofa" Ni :

# Oro Ilorin Pelu Igbomina Kise Ija

Olotu, a dupẹ lọwọ nyin fun ọpọlọpọ iwe akọkun ti OLOFINTOTO "Eleti-Ọfe" kọ fun wa laipe yi lori ọrọ awa ara Ọffa, Igbomina, Ekiti, Ibọlọ ati Ijọba ibilẹ ilu Ilọrin ti o ti fẹ fi igba kan da bilisi silẹ, ti o ni o ṣẹ ndi ọrọ suru diẹdiẹ nisisiyi.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

**Wo oju ewe kefa fun oro IYERUOKIN Omo Olofamojo ti o ni, ORO ILORIN pelu IGBOMINA kise oro IJA.**

PHILIPS
for RADIO
PHILIPS

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELGERAM

28 Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI–ỌFẸ" LAGOS

P O. Box 468 Phone 23370

VOL. XIV. No 845, SATURDAY. NOV. 17, – NOV 23, 1962


# Asakasa Ni Eleyi

Awọn Yoruba mọni-mọni ni "ara ile ẹni ni pee ni amodi, arun ni awọn ara ita mba ni pee ," iyẹn ni ti iwe kan ti arabinrin kan kọ si wa lori ọrọ aṣa buruku kan ti awọn obinrin wa l'Eko nhu ti nwọn ba lọ si ibi igbeyawo tabi ibi isinku. Aṣa yi buru tobẹgẹ ti o ti sọ ọpọlọpọ di onigbese tabi ẹlẹwọn.

Aṣa buruku na ni ti ọti ti awọn obinrin wa ma nfa lọwọ ti nwọn ba ti lọ ba oloku se oku. Yala o ni owo lọwọ, o ko ni lọwọ, o ni lati ra ọti sitaotu (stout beer) fun gbogbo awọn ti nwọn ba yọsọ leka wa, ki nwọn ba le ri owo san owo aṣọ ti nwọn lọ fi ọpa re wale lati ọdọ anti ti o nfi aṣọ haya.

## Agbere

Arabinrin ti o kọwe wa na ni on ti ba ọkọ on lọ ṣe iṣẹ ni idalẹ bi Oke-Ọya ati Ipinlẹ Ila Orun ni ilu awọn Ibo, iru aṣa buruku yi ko si nibẹ rara.

Ni aiye atijọ ti a ba ni ọrẹ tabi ibatan ti oku ba ku fun tabi o fẹ ṣe igbeyawo, owo ni awọn agba atijọ fi nta oluware lọrẹ kiṣe gbese, sugbọn ti aiye ode t'oni kọ ni aṣa a nran ara wa lọwọ yi.

## Ati Ainitiju

Bi oku ba ti ku gbara nisisiyi olukuluku awọn obinrin a ni ije si, onjẹ de! O kere, o pọ, awọn a ri kọbọ kọbọ gba fun owo ẹbẹ, ti o ba di ọjọ ijade oku awọn yio ri ọti gba wa si ile fun tita. Ọdọ awọn Obinrin wa Imale ni aṣa na pọ pupọju si.

Iru aṣa ainitiju bayi ko dara, ile ni o ntu, nitoripe ẹkọ kẹkọ ni awọn obinrin wa yi nkọ ara wọn nibẹ pẹlu agbere ṣiṣe. Eleyi paapa ni o nmu ki awọn ọmọbinrin ile iwe ya iyakuya ninu agbere ṣiṣe.

Ẹnikẹni ti o ba leti lati gbọ, ki o gbọ!

# Iwe Si Olotu

## Asakasa Wo Ilu Eko

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe nyin lati tọka aṣakaṣa kan ti mo ṣe akiyesi lọwọ awọn obinrin Eko - iyẹn ni ti ọti sitaoti (Stout beer) ti nwọn ma ndi mọ iborun ti wọn ba ti lọ ba Oloku ṣe oku.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa tẹ mọ wọn leti wipe aṣa yi ko dara. Emi ti ba ọkọ mi lọ si idalẹ bi Ẹnugu, Pọta, Kano ati Kaduna ni Oke Ọya, emi ko ri ibiti nwọn gbe yapa to ilẹ Yoruba.

Aṣa a nlọ fi owo ya aṣọ ti a ko le ra lati fi ṣe ẹṣọ sara paapa ko dara. Agbere ni o nmu wa, o si tun mba ile jẹ. Boya ẹ le sọ wipe pipẹ ti mo pẹ ni idalẹ ni o jẹki nma sọ eyi. Bẹni, sugbọn aṣa yi ko nṣe ti ọmọluwabi o si yẹ ki a yẹ ṣee ti a'ko ba fẹ gba oruko buruku.

Emi ni,
Iya - afin Emili

Suru - Lere,
Eko

## Oti Bolugi

Ẹba wa kesi awọn alaṣẹ ilu Ijẹsha ki nwọn ṣe ikilọ fun awọn ẹlẹmu ti o nda ọti-Bọlugi sinu ẹmu wọn ki nwọn yee ṣee ti nwọn ko ba fẹ pa ara ilu nitoripe ko nṣe gbogbo wa ni o mọ ọti bọlugi na mu.

Emi ni,
Ilesha M. Adelakun


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

NOTICE OF INVITATION TO TENDER

Construction of Junior Service Quarters and Various site works at Port Harcourt, Eastern Nigeria.

The Nigerian Ports Authority announces its intention to invite tenders for the following works at Port Harcourt :-

The construction of 24 blocks of 4 quarters each on a site in Port Harcourt. There are existing on the site various buildings which have to be completely removed before constrution can commence on the new buildings. Included in the site works are roads, paths, water supply reticulation system, sewers and surface water drains.

Contractors who have the requisite experience, staff and plant to undertake these works are invited to apply to the Authority's Chief Engineer, 216, Broad Street, Lagos, to be included in the list of those to be invited to tender. The application must be supported by evidence of the required experience, staff, plant and financial background. Photographs of works which have been undertaken by the contractor in the past 2 years will be of assistance.

The Authority reserves the right to select a short list of Contractors to be invited to tender and will not enter into correspondence with any not selected. Canvassing will disqualify the applicant.

The site may be viewed by appointment with the Port Engineer, Port Harcourt.

The closing date for applications will be 26th November, 1962.

N.P.A. Notice No. 841
12th November, 1962.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

LATI ỌWỌ AYILUKA

**Owode**

Ẹnyin ara mi, mo gbọ wipe awọn "Oyinbo alawọdudu ti o mba wa ṣe Alamojuto


FIAT





**The new versions of the 1100**

export saloon    special saloon    station wagon

PRICES

| | Ex Lagos | Ex Turin |
|---|---|---|
| EXPORT SALOON | £680 | £398 |
| SPECIAL SALOON | £750 | £450 |
| STATION WAGON | £800 | £490 |

Quality and price are the driving power of Fiat success – The fullest range of cars of a single Make: from the small 500 D and 600 D cars to the 1100, the 1300 - 1500, the 1500 S cabriolet and the 1800 B - 2300 – Fiat: more than ever the car for everybody.

VISIT OUR STAND NO 246
AT THE TRADE FAIR.

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS (EB). IBADAN. KANO. KADUNA. JOS. PORT HARCOURT. ABA.


Ijọba Apapọse wa nisisiyi ti da nkan nran sile nilu Eko lori iwe ti Ijọba Apapọse na tẹ jade wipe awọn tun fẹ gba ile ati awọn ilẹ kan si ni igboro ilu Eko.

Ni Isale Eko, Olowogbowo, Okepopo ati Isalegangan ni mo ti gbọ wipe olukuluku ti npe ipade ọmọlẹbi ti awọn ara Eko npe ni FAMILY MEETING lati mọ bi awọn yio ti se pin owo ti Ijọba yio san fun awọn ti awọn ba ti gba ile tabi ile awọn si

Mo gbọ wipe ni alaiti gba owo na awọn kan ti mba ara wọn ja, awọn kan ni awọn fẹ ri iwe - ọjọbi olukuluku ọmọ ti baba awọn bi lati mọ ọmọ ọkọ ti owo na ba tọsi.

Owode, sugbọn ki o to jẹ ogun wa pitan danadana.

## Emu Aran

Ọrẹ mi, awọn kan ni ile awọn ara wa ni ilu Ibo ti da ẹgbẹ AGBẸMUYỌ sile ni Enugu ati jake jado ipinlẹ na, Oloyẹ B L Okwu tiṣe Minisita Alamojuto eto Ilera Ipinlẹ Ila Orun na si ti fi owo si ẹgbẹ na. O ni ko si ọti ti o dabi ọti ẹmu–aran.

Minisita yi ni bi o bi nle mu aha ẹmu kọkan lojumọ nṣe ni oju rẹ a mọ lẹ gedegbe, wa ma rihin r'ọhun. Mo gbọ, mo gba, boya aha ẹmu kọkan ti awọn Hausa ki mu ni asiko ni asiko ni o fa a ti afọju (Mekafo) fi pọ repete ni ilu wọn.

## Fun Afọju

Mo gba a ni imọran ki awọn ẹgbẹ ọdọ Oke Ọya tete kọwe ebẹ si Alhaji Amọdu Bello, Sardauna Sokoto wipe awọn fẹ mọ mu aha ẹmu-aran kọkan nilu awọn nitori ogun oju ni omi ti o njade lara igi ọpẹ, ọpọlọpọ awọn ọmọ Igbomina ni awọn si mọ ẹmu - aran bẹ, eleyi a si jẹ ki owo tun wọ ilu fun awọn ti ko kuro nile

(Wo iyoku loju ewe kejo)

# Oro Ilorin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ṣugbọn nkankan ni mo fẹ ki ẹnyin ọkawe mi mọ daju, eleyini ni pe suru ni obi o si ni akọ. Ọrọ awa pẹlu Ijọba ibilẹ Ilọrin kiṣe ọrọ ija rara, awọn kan ti ko fẹ mọ bi awọn nkan ti nlọ si ninu aiye ti a wa yi ni nwọn nfẹ ba nkan jẹ. Nwọn ti gbagbe wipe bi a ti bi ẹru ni a se bi ọmọ.

Ẹnyin ara mi, ẹru kan ko tilẹ si ni ibi kan mọ ni ode aiye ti a wa yi, a fi ti a ba ntan ara wa jẹ.

## Inira

A gbọ ti awọn ẹnikan ti ko mọ nkankan nfọn ẹnu kakiri igberiko Ilọrin wipe bi o ba ti gba ni awọn yio ṣe se e, amunisin ara Ilọrin ni awọn Igbomina a jẹ titi lai. Nwọn le mọ iwe ki nwọn tun mọ ohunkohun.

A gbọ wipe nitori ileri wọn na ni nwọn ko ṣe yọnda fun Gomina Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti o wa si Ilọrin ni aipẹ yi, ki o de agbegbe ilu Igbomina rara ki nwọn mọ le ri ọna lati sọ iru inira ti awọn nri fun lọdọ awọn Ijọba ibilẹ.

Ẹnikẹni ti o ba jẹ Ọlọgbọn ti o si nse akiyesi bi aiye ti nlọ si ni ode isisiyi a mọ wipe aiye ti kuro ni AIYE MA ṢE Ọ, OJU RẸ A JA A. Bi a ti b'ẹru ni a b'ọmọ eda kan ko ja wa lati oju ọrun. Awọn ti o jẹ alagbara lode isisiyi mẹlọmẹlọ ni nwọn nṣe. Ọna lo jin, ẹru paapa ni baba.

Ọlọla Ahmadu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa paapa fi igba kan sọ wipe awọn se akiyesi wipe awọn kan ti awọn fi si idi iṣẹ Ijọba ibilẹ tabi ti Ipinlẹ nṣe oju saju fun awọn kan. Ọpọlọpọ wọn ni nwọn si nṣi aṣẹ ti awọn fun wọn na lo. Awọn ko rau wọn ni iru iṣẹ bayi.

Eleyi dara pupọ lati gbọ leti, ṣugbọn iani bi oluwa rẹ ti yio sọ fun wọn wipe nkan ti awọn alaṣẹ Ijọba nṣe ko dara. O bẹrẹ lori dandoka Ọba titi ti o fi de ọdọ akọwe kotu Alikali. Nkan ti nwọn ba ṣe a-segbe ni.

Nko le ba ọmọ wa ti o kọwe lati ilu Oyinbo wa wi pe awọn ti awọn wa lẹhinod: awọn ko mọ bi ọrọ na ti nlọ si tabi o ṣẹ nrẹ awọn alagba wa ni. Bi enia ko ba bere idi ọrọ nitotọ oluwarẹ ko ni mọ bi gbogbo rẹ ti nlọ si.

O yẹ ki ẹru-jẹjẹ ba awọn enia wa, paapa awọn asiwaju wa ati awọn ijoye wa ti nwọn wa nile. A gbọ nigba kan ti nwọn ni ki awọn ijoye wa kan mọ wa fi ọwọ si iwe wipe awọn ko lọwọ ninu ki a yan Ijọba ibilẹ fun wa.

Diẹ ninu awọn asiwaju wa ti nwọn wa ni idalẹ si wa ninu awọn ti o nwa oju-re awọn ti nfi iya jẹ wa. Mo fi oruko bo wọn ni asiri ni, gbogbo wọn ni a mọ ti nwọn nsọ wipe TẸ SIBI AIYE BA TẸ SI ni awọn da nisisiyi. Agba di ọwọ nyin o, ẹnyin enia wa.

Emi Iyeru Ọkin ọmọ Ọlọfa-mọjọ ni ọrọ awa ọmọ Offa mọ Igbomina pẹlu Ekiti parapọ kiṣe ija rara, ti nwọn ba nfẹ irẹpọ ki nwọn fa wa mọra ki nwọn fun wa ni awọn nkan ti a nfẹ.

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kavachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

# Sardauna Ko Awon Egbe Oselu Ariwa

## Kan Ti O Fe Dapo

KADUNA—Ọlọla Amodu Bello Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa tiṣe aṣiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Alaake (NPC) fi aake kọri o si kọ lati gba wipe ki awọn ọmọ ẹgbẹ Ariwa UMB ti Ọgbẹni Tarka, ti nwọn ti fi igba kan dapọ mọ ẹgbẹ Afenifẹre (AG) dapọ mọ awọn ọmọ ẹgbẹ on. Awọn ọmọ ẹgbẹ na ni awọn ko ba ẹgbẹ Afenifẹre se mọ awọn fẹ di ọmọlẹhin awọn NPC ẹgbẹ Alaake.

Ọlọla Bello ni kiṣe ọna oko kanna ni awọn nsan, nitoripe nkan ti awọn nfẹ ni Ipinlẹ Ariwa ni "Ọmọ onilẹ lo nilẹ" nitoripe Ipinlẹ na ko si fun "iru wa ogiri wa" ti awọn ọmọ UMBC ti Tarka mba kiri.

Ṣaju eyi awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu yi ti ṣe ikede fun gbogbo araiye wipe awọn tiṣe ipinnu nibi ipade kan wipe awọn ko ba ẹgbẹ Afenifẹre (A.G) ṣe mọ rara.

# Okunrin Ti O Pa Iyawo Re Ku Sinu Igbo

IKIRE — Ọdọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Lasisi Iṣhọla ti o ṣẹṣẹ jade kuro ninu ọgba ẹwọn ni a gbọ wipe o ṣa iyawo rẹ Aliratu Abẹo pa, on na si lọ ku sinu igbo kan nibiti o gbe lọ sa pamọ si.

Bayi ni alaye ti onirohin wa sọ nipa ọrọ na: Abẹo jẹ iyawo Ishọla ki nwọn to juu sẹwọn. Nigbati o wa lẹwọn ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Rafiu Akanni ti o ngbe Opopo Ọdẹyinka ni Ikire ti gba iyawo rẹ ti o njẹ Abẹo.

Nigbati awọn Ọlọpa da a silẹ ni ọgba ẹwọn ti o de'le ti ko ri iyawo rẹ, ti nwọn sọ wipe ọkunrin kan ti gba a lọ, ni o ba lọ sibẹ ti o lọ ṣa iyawo na pa patapata, o tun kọju si ọkọ tuntun ti obinrin na fẹ o gun lọbẹ, o wa salọ sinu igbo.

Awọn Ọlọpa ni riri ti awọn ri oku rẹ ko jọ ẹniti o pa ara rẹ, boya enia kan agbọrandun ni o gun Ishọla lọbẹ nibiti o gbe sa si.

# Kuku Ti O Lu Oga Re Fi Owo Tanran

YABA — Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ni ki Kuku Oyinbo kan ti o njẹ Simeon Akalonu ti o ngbe Oke-Ira ni Ọgba Reluwe ni Ebute-Mẹtta fi ponun mẹdọgbọn (£25) tanran tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu meji fun nina ti o na Oyinbo ọga rẹ ti orukọ rẹ njẹ Joseph Alexander Vaz, Ọga ile iṣẹ ni Loko (Nigerian Railway).

Ejọ ti awọn ọlọpa ba kuku Oyinbo na ro ni wipe ọga rẹ ni on ko fẹ arufin yi gẹgẹbi Kuku on mọ, ki o mọ lọ. Eleyi bi Kuku na ninu pupọ, o ni ki on to le kuro lọdọ rẹ a fi ti oyinbo yi ba san owo oṣu mẹta fun on.

Kuku yi ni ko tilẹ to iwe - ẹri buruku ti ọga na gbe le on lọwọ pe iwa on ko daru, eyi lo jẹ ki on da ẹṣẹ bo loju ati ni imu.

## Nwon Ntun Enia Ka Ni Ilu Awon Hausa ?

ENUGU — Ni ijeta ni-ɹu ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ Ila-Oorun, awọn aṣoju ti awọn ara ilu ran lọ si Igbimọ na fẹnu kan ọ r ọ awọn enia ti awọn ara Ipinlẹ Ijọba Ariwa (Hausa) tan y a n j a d e lati m a k a kakiri si lehinti nwọn ti pari a nka enia (Census) l a t i iwọn nkan bi oṣu marun.

Oloye Ignatius Morphy, aṣoju Ilu Ogoja ni i l e Igbimọ ni idi ọrọ enia kika ti nwọn ko jẹ ki a mọ iye ti nwọn ka wa ti ko ye awọn si rara. O ni o dabi ẹni wipe nkan kan nbẹ nidi ọrọ na.

O ni o pẹ niwoyi ti Mallam Waziri Ibrahim Minisita Alamojuto nkan idagbasoke Ijọba Apapọ ṣe, so fun gbogbo agbaiye wipe awọn ti o fẹ tan lati gbe iyọrisi enia kika na si gbangba ati pe awọn enia ti o wa ni Ipinlẹ Ariwa ko ju 30 million lọ. Awọn ṣe akiyesi pe abumọ wa nibẹ ki awọn Hausa ba le ma jẹ gaba lori awọn ipinlẹ yoku.

Gbogbo awọn ọmọ ilu Ibo ti o ti nṣe iṣẹ ni Oke Ọya ni nwọn ti le wa sile nitoripe awọn ọmọ awọn (Hausa) ni awọn fẹ fun iṣẹ awọn. Iru awọn bayi ti nwọn le wa sile ni awọn ti njẹ ki awọn enia ti nwọn ri ... ni Ipinlẹ na pọ. Nibo ni awọn ti tun ri awọn enia ko mọra ?

Oloye Morphy sọ fun gbogbo ijoko igbimọ na pe ... ni awọn ara wa ni Ipinlẹ Ariwa na nsọ ... awọn nfẹ irẹpọ gbogbo Ipinlẹ Ijọba yoku nitoripe awọn ko bu iwa rẹ rara. Kini o tun fa enia kika kiri yi ni ilu Hausa ;

---



**A recent study of Viscount Linley, son Her Royal Highness Princess Margaret the Earl of Snowdon, who is one year old on November 3.**

**This delightully informal picture was taken by the Earl of Snowdon.**

At Random Notes

# At The Trade Fair

BY "THE JOTTER"

Tomorrow is the last day of the NIGERIAN INTERNATIONAL TRADE FAIR which started about three weeks ago on Vitoria Island, Lagos. Before the the manufacturer' representatives do their packing up, I took the final worm's eye views of the many pavilions, this time with a well known personality in the person of Senator the Hon. Dr. M. A. Majekodunmi Administrator of Western Nigeria. Dr. Majekodun who is also Federal Minister of Health was accompanied by some of his Commissioner.

( Continued on page 8 )

## India Government Issues Warning

INDIA— The Government of India have, in a recent notification prohibited the sending out of India by sea, land or air, articles fo the following descriptions:-

All tickets, coupons, advertisements, notifications to prize-winners relating to a prize competition or lottery which has not been authorized by law; posters, letters, lists of lucky winners relating to any Gift Scheme in India which is not authorized by law, announcing to residents of countries abroad that an individual has been a lucky winner and asking him to remit money, for any reason, for the despatch alig ft; poster relating to any Money Circulation Scheme which is not authorized by law which invites residents of countries abroad to remit money for becoming beneciarios of returns many times higher than the investment.

This measure is yet another effort on the part of the Indian authorities to curb the undesirable activities on the part of some anti-social elements in India who have in the past managed to succeed in misleading and taking advantage of some residents of some countries abroad.

Residents in Nigeria who receive, through the post, any material of the nature specified earlier, should take warning and not acknowledge or, in any way, act upon it.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

LATỊ ỌWỌ AYILUKA
(O bẹrẹloju ewe karun)

Oloye Okwu, o ṣe pupọ, emi Ayiluka paapaa e sọ fun Baba ẹlẹmu mi, awọn bi Samu Ọdẹ ni Ọlọpomẹrin, Adayidun ni Okesuna l'Eko ati Iya Mulika ni Ogunpa Ibadan, ki awọn na gbọn ọwọ si ẹmu wọn nitoripe emu-aran ti bẹrẹsi gbayi ti nwọn ko ba fi omi jẹ a.

## Emu Ilesha

Mo gbọ wipe awọn akọwe Wole-wole onimọtoto tiṣe ikilọ fun awọn ẹlẹmu Ilesha ti nwọn nda ọti bọlugi sinu ẹmu wọn ki o le ni agbara wipe ẹ'ẹmu ti awọn ba mu pẹlu iṣẹ buruku yi ewọn ni oluwarẹ nlọ.

Mo tilẹ ṣebi ara Ilesha ẹmi ni nwọn nmu, nigbawo ni nwọn tun di ẹniti o'nmu ọti bọlugi. Tabi a ri ọmọ Ijẹsha ti o fẹ iyawo lati ilu Sobo ni? Ara Ilesha, ẹmu lẹ mu o!

## Baba "Yaro"

Anu ṣe mi pupọ lati gbọ iku arakunrin wa Ọgbẹni K. B. Savage ẹniti gbogbo wa mọ ni "BABA oni YARO" ti o jalaisi ni aipẹ yi ni ile rẹ ni Alakukọ, Ijero, Ebute-Metta. Ẹni ọdun marundinladọrin ni arakunrin na, o si jẹ ẹniti o f'ẹran ẹbi ati ọrẹ pupọ, bi o ti nṣe fun alejo, bẹni o nṣe fun onile.

KBS jẹ ẹniti ọpọlọpọ awọn abiyamọ ilẹ wa ati ilu miran ni agbegbe ọdọ wa ko le gbagbe lailai fun agbo inu igo ti nwọn pe ni "YARO" ti o ṣe fun wọn. Ọpọlọpọ si ni awọn ọdọmọde lọkunrin ati lobinrin ti o wa lẹnu iṣẹ loni ti nwọn ko fi agbo "YARO" yi rọ.

KBS., Ọrun re!

### At Random Notes

# At The Trade Fair

BY "THE JOTTER"

(Continued from page 7)

Before the scene was shifted to the Western Region pavillion for an affair which one could describe as WESTERN REGION TRADE FAIR DAY; the Administrator visited many foreign Government pavillions such as Russian, Poland, Rumania, Germany, Canada, British, U. S. A., Israel, and Holland.

## At India

The goods produced by India varied from textile goods up to cloth weaving machines, electrical accessories, fans, rice mills, flour, cotton and jute manufactures and so on. I understand that Indo-Nigerian trade is experiencing an upward trend and the famous slogan in India is "Build Machine, Build India," and had built so many machines for their tools.

## Hong Kong

I understand that Hong Kong carvings are being exported to many parts of the world. The ivory carvers of this British Colony of Hong Kong are passing on their skill from one generation to another generation.

I was shown a wide range of carvings including lamp-shades, houseboats, human figure on horse back and all Chinese gods.



## Western Region

In fact, Western Region pavillion is envy of all. Inside that Pavillion I saw cocoa (the wealth of that Region) being displayed in bags and palm kernel products. Yoruba cloth weavers from Ọyọ and Iseyin gave us a good demonstration of new pattern in local weaven clothes.

Other distinguished visitors to the Fair this week were Sir Francis and Lady Ibiam, the governor of Eastern Nigeria, who, accompanied by Minister of Commerce and Industry Zenna Bukar-Diphcarima and the Director of the Fair, Mr R. H. C. Hammond toured the International Trade Fair.

## Dokita Maja Kekere Tu Asiri

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Dokita Maja ni igbati on de ọdọ Awolọwọ on yanju ara on, on sọ fun wipe ni ti on iwa buruku ti awọn oṣelu wa nhu jake jado nṣe ni o dabi ẹni wipe ki on ko wọn da sinu ile kan, ki a dana sun wọn patapata

(Wo iyoku loju ewe keji)

Y/C November December 1962.

Ra

YORUBA CHALLENGE

November - December

Fun

Aworan Igboro Eko
Orin Keresimesi

Ati

Itan o'itọ aladun niti-
"Olorin ti O pade
Olugbala".
Iwe oloju 24 yi ko le'wo

4d pere ni
iwe kan

E Polowo Oja
Yin Sinu Irohin
Eleti—Ofe
Losose

## Eka Itan Alake

Loju ewe Karun

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU) ỌLA ONATADE
15, Kosoko Street, Lagos.